Àkóónú

Àkiyèsí		ii
Àkóónú		iii
Samuel Obalolu Oke & Olaide Ridwan Jimoh	Àtúnyẹ̀wò Sílébù Olóhùn Òkè (Soo) ní Ẹ̀ka Èdè Arigidi	1
Ọmọ́wúnmi Ọmọ́ṣọlá Iyawe, Olúfadékẹ́mi Adágbádá & Moses Adédire Adékúnlé	Ojúwòye Àwọn Òǹkọ̀tàn Ìtàn-Àròsọ Yorùbá lórí Ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín Ojúṣe Òbí àti Àìsáàbò ní Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà	18
Olaide Akinwande	Àgbéyẹ̀wò Ìjẹyọ Atọ́ka Ìyísódi nínú Orúkọ Àbíkú	38
Monisọ́lá Rónkẹ́ Fáladé	Pọ́n-Na: Àtiwáyé àti Ìṣẹ̀dá rẹ̀ nínú Ewì Yorùbá	52
Ọládiípọ̀ Ajíbóyè	Ìlọsíwájú Èdè Yorùbá àti Ipa tí Ìmọ̀ Ẹ̀rọ ń kó lórí rẹ̀	71
Ibrahim Àbàyọmi Adeigbe	Ọgbọ́n Ìṣèwádìí nínú Lítírésọ̀ àti Èdè Yorùbá	83
Roheemat Ọlábímpé Adéyẹmí	Ìfìwádìí-Sọ̀tumọ̀ àwọn Ìyánrọ́fẹ́ẹ́rẹ́ inú Oríki Ọba Ládigbòlú Kìnnì àti Adéyẹmí Kẹ̀ta	101

LÁÀŃGBÀSÀ Nọ́mbà 25 Ọdún 2025 ISSN 0794 - 3881

LÁÀŃGBÀSÀ

(Jọ́nà ìṣẹ́ Akadà ní Èdè Yorùbá)

ISSN 0794 - 3881

University of Lagos

Nọ́mbà 25 Ọdún 2025



LÁÀŃGBÀSÀ
(Jọ́nà iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá)

University of Lagos

Nọ́ńbà 25 **Ọdún 2025**

Láàńgbàsà

Olóòtú Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọládiípọ̀ Ajíbóyè

Olùdámọ̀ràn Ìgbìmọ̀ Olóòtú:

Ọ̀jọ̀gbọ́n Yẹ́misí ADÉBỌ̀WÁLÉ

Ọ̀jọ̀gbọ́n Micheal ABÍỌ́DÚN

Ọ̀jọ̀gbọ́n Lérè ADÉYẸMÍ

Ọ̀jọ̀gbọ́n Fọ́lọ́runṣọ́ ÌLỌ̀RÍ

Ìsọ̀ǹgbè Àtẹ̀jáde: Ọ̀mọ̀wé Ẹniọlá LÁDÍPỌ̀

Àkíyèsí

Bí o bá fẹ́ kí ọ̀rọ̀ àpilẹ̀kọ iṣẹ́ ìwádìí rẹ jáde nínú Láàńgbàsà, àwọn ohun tí o ní láti ṣe ni wọ̀nyí:

(i) Fi àkọtọ́ Yorùbá òde-òní kọ àpilẹ̀kọ rẹ, kí o sì fi ránṣẹ́ sí laangbasa23@gmail.com pẹ̀lú ẹgbẹ̀rún mẹ́wàá náírà (N10,000) owó ìyẹpépà rẹ wò.

(ii) Lórí tákàdá A4 ni kí o tẹ pépà rẹ sí, kí ó má sì gùn ju ogún ojú-ìwé lọ pẹ̀lú ààtò 2.0 ní àárín ìlà kan sí èkejì.

(iii) Kọ gbogbo àwọn ìwé ìtọ́kasí sílẹ̀ ní ṣíṣẹ-n-tẹ̀lé lẹ́yìn àpilẹ̀kọ rẹ ní ìlànà ti APA. Bákan náà, àpilẹ̀kọ rẹ gbọdọ̀ ní àṣamọ̀ tí kò gbọdọ̀ juọ̀tà lé nígba dín mẹ́wàá ẹyọ ọ̀rọ̀ lọ kí ó sì ní kókó-ọ̀rọ̀ márùn-ún.

(iv) Owó àtẹ̀jáde pépà tí a bá gbà wọlé: ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọgbọ̀n náírà (N30,000).

Àkóónú

Àkíyèsí		ii
Àkóónú		iii
Samuel Obalolu Oke & Olaide Ridwan Jimoh	Àtúnyẹ̀wò Sílébù Olóhùn Òkè (Soo) ní Ẹ̀ka Èdè Arigidi	1
Ọmọ́wùnmí Ọmọ́ṣọlá Iyawe, Olúfadékẹ́mi Adágbádá & Moses Adédire Adékúnlé	Ojúwòye Àwọn Òǹkọ̀tàn Ìtàn-Àròsọ Yorùbá lórí Ìbáṣepọ̀ tó wà láàárin Ojúṣe Òbí àti Àìsáàbò ní Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà	18
Ọlaide Akinwande	Àgbéyẹ̀wò Ìjẹyọ Atọ́ka Ìyísódì nínú Orúkọ Àbíkú	38
Monísọ́lá Rónkẹ́ Fáladé	Pọ́n-Na: Àtiwáyé àti Ìṣẹ̀dá rẹ̀ nínú Ewì Yorùbá	52
Ọládiípọ̀ Ajibóyè	Ìlọsíwájú Èdè Yorùbá àti Ipa tí Ìmọ̀ Ẹ̀rọ ń kó lórí rẹ̀	71
Ibrahim Àbáyọ̀mí Adeigbe	Ọgbọ́n Ìṣèwádìí nínú Lítírẹ́ṣọ̀ àti Èdè Yorùbá	83
Roheemat Ọlábímpé Adéyẹmí	Ìfìwádìí-Sọ̀tumọ̀ àwọn Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ inú Oríki Ọba Ládìgbòlù Kìnní àti Adéyẹmí Kẹta	101

ÌFÌWÁDÌÍ-SỌ̀TUMỌ̀ ÀWỌN ÌYÁNRỌ̀FẸ́ẸRẸ́ INÚ ORÍKI ỌBA LÁDÌGBÒLÙ KÌNNÍ ÀTI ADÉYẸMÍ KẸTA

Roheemat Ọlábímpé **ADÉYẸMÍ (Ph.D.)**
Department of Linguistics &Nigerian Languages
Faculty of Arts
University of Ilorin, Nigeria.
adeyemi.ro@unilorin.edu.ng
orcid:https://orcid.org/0009-0006-1839-4134

Àṣamọ̀
Bí a bá ta á, à á tọ̀ ọ́ ni, kó má baà dẹran onídin. Ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ló ti lọ lórí ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú lítírẹ́ṣọ̀ alohùn Yorùbá ṣùgbọ́n, àkíyèsí wa ni pé, kò tí ì sí́ ẹni tó ṣiṣẹ́ lórí ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú àwọn oríkì Aláàfin Ọ̀yọ́. Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ sì ni àwọ́n ọ̀nà tí à á fi í pàṣamọ̀ ọ̀rọ̀ nínú afọ̀ lái tú iṣu dé ìsàlẹ̀ kòkò tí kò sì ní pa ìtumọ̀ afọ̀ lára. Ọ̀pọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti wáyé ló kórajọ di oríkì tí ó sì jẹ́ pé gbólóhùn àti ọ̀rọ̀ pọ̀ níbẹ̀ tí wọ́n lóyún ìtumọ̀ sínú. Èròńgbà iṣẹ́ ìwádìí yìí ni láti le tọpinpin àwọn ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ oríkì Aláàfin Ládìgbòlù kìíní àti Aláàfin Adeyẹmi kẹta torí pé àwọn méjèèjì ni wọ́n pẹ́ jù lórí àpèrè babaa wọn nínú àwọn Aláàfin méjẹ̀èjọ tí wọ́n ti jẹ ní Ọ̀yọ́ ìsìnyí láàrin ọdún 1835 sí 2022. Isẹ́ yìí tọpinpin àwọn ìtumọ̀ yìí nípa ṣíṣe àmúlò tíọ́rì ìfiwádìí-sòtumọ̀ (Hermaneutics). Ọgbọ́n ìsọ̀tàn O-ṣojúù-mi-kòró ni a gbà fi gbé iṣẹ́ náà kálẹ̀ gẹ́gé bí akópa nínú oríki Aláàfin Ọ̀yọ́. Iṣẹ́ yìí fi múlẹ̀ pé, ọ̀pọ̀ ìtàn ló kẹnú sínú oríkì àwọn Aláàfin tí ó sì yẹ kí á ṣàlàyé rẹ̀ fún ìtẹ̀síwájú iṣẹ́ ọ̀nà aláwòmọ́ lítírẹ́ṣọ̀ Yorùbá.

k**ókó-ọ̀rọ̀**: Aláàfín, ìfiwádìí-sòtumọ̀, Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́, Oríkì, Ọ̀yọ́

1.0 Ìfáárà

Tí kò bá nídìí obìnrin kìí jẹ́ Kúmólú, èyí tó bá jẹ́ Kúmólú a jẹ́ pé ikú ti p'Akọni ilé e wọn ni. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ ló ma ń wà nínú oríkì nílẹ̀ Yorùbá tí wọ́n sì máa ń ní ìtumọ̀ tó rọ̀ mọ́ wọn. Ọ̀pọ̀ àwón ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ló sì nílò ìtumọ̀ pẹ̀lú ìwádìi ìjìnlẹ̀ kí àwọn ará àwùjọ leè mọ húlẹ̀húlẹ̀ irú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ ṣe pàtàkì púpọ̀ nínú oríkì torí pé nínú rẹ̀ ni a ti lè ṣàwárí àwon ohun tó pamọ́ tó sì wúlò láti mọ̀ fún ìtẹ̀síwájú ìmọ̀ tórí bẹ́ẹ̀ ni ó ṣe ṣe pàtàkì láti wádìí àwọn ohun bẹ́ẹ̀.

Gẹ́gẹ́ bí àríwòye orúkọ yìí gan-an, Ì-YÁN-Ọ̀RỌ̀-FẸ́ẸRẸ́ túmọ̀ sí àwọn ọ̀rọ̀ tí a kò sọ tán tàbí tí a kàn mẹ́nubà léréfèé lái túṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò. Bí ó ṣe rí rèé nínú oríkì àwọn Aláàfin Ọ̀yọ́ tí Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ kún inú

wọn bámúbámú. A wá yan oríkì Aláàfin méjì láyò torí pé a gbà pé bí ọba bá ṣe pẹ́ sí lórí ìtẹ́ ni ìtàn wọn ṣe máa ń pọ̀ sí látàrí ìríri tí wọn ti ní èyí tí ó parapọ̀ di ìtàn fún wọ́n. Ìdí nìyí tí a sì fi ṣàmulò tíọ́rì ìfiwádìí-sòtumọ̀ kí ó le baà mú iṣẹ́ náà lóòrìn dáadáa torí pé òun ni yòò ṣe iṣẹ́ ìtọpinpin ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ tó ṣókùnkùn ọ̀hún.

1.1 Èrèdí iṣẹ́ ìwádìí

Èrèdí iṣẹ́ ìwádìí ni láti ṣe àfihàn àwọn ohun tó forímù nínú oríkì àwọn Aláàfin tí a yàn láàyò. Oríkì àwọn Aláàfin jẹ́ ọ̀kan nínú lítírẹ́ṣọ̀ alohùn Yorùbá tí kò fi bẹ́ẹ̀ hàn síta nítorí pé ó ṣòro díẹ̀ fún àwọn aṣèwádìí láti rí oríkì náà gbà sílẹ̀ láti ẹnu àwọn apohùn tí wọn ma ń ki Ọba torí tí wọn ń gbé inú Ààfin tí wọ́n sì ṣòro láti rí fún iṣẹ́ iÀwọn ohun mánigbàgbé ní ó kún inú àwọn oríkì yìí fún ìtẹ̀síwájú ìmọ̀, ìdí gan-an sì nìyìí tí a fi gbé iṣẹ́ yìí jádé kí àwọn ohun tí a gbà pé wọ́n jẹ́ àmù àṣà Yorùbá báwọ̀nyìí má baà fọ́ tàbí kí ó gbẹ.

1.2 Àgbéyẹ̀wo iṣẹ́ àwọn Aṣáájú

Ní tòótọ́ ni pé àwọn onímọ̀ lọ́kan-ò-jọ̀kan ni wọ́n ti siṣẹ́ tabua lórí Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́, lára wọn ni, Wolf (1962), Babalola (1966), Finnegan (1977), Olatunji (1984), Ilesanmi (1989 ati 1990), Ajayi (1995), Agbaje (2001) àti Olawale àti Aransi (2015). Bí àpẹẹrẹ, Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú oríkì orílẹ̀ àwọn òba Aládé Èkìtì ni Ajàyi (1995) ṣiṣẹ́ lé lórí, nígbà tí Olawale àti Àránsí ṣe tiwọn lórí àwọn ìlú ajórúkọmọ́-Ifọ́n. Àwón iṣẹ́ yìí àti àwọn mìíràn tí a ti rí tẹ́lẹ̀ kún dáadáa ṣùgbọ́n a wá ṣàkíyèsí pé kò sí ẹni tó ṣiṣẹ́ lórí Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú oríkì àwọn Aláàfin. Tí ọ̀rọ̀ bá wá rí báyìí, kín ni àwọn onímọ̀ wọ̀nyìí wá pè ní Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́? Babalola (1966, o.i 4-12) sọ nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé àbọ̀ ọ̀rọ̀ ni a lè pe Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́, ó ní oríkì orílẹ̀ máa ń farasin nígbà púpọ̀ nítorí pé èdè oríkì báyìí fara jọ èdè awo…fẹ́rẹ́fẹ́rẹ́ ni oríkì náà yóò máa yán ìtàn àtijọ́, àlàyé kíkún yóò sì kù sí ọwọ́ ìwádìí àti ìtọpinpin ọ̀rọ̀ … àwọn oríkì-orílẹ̀ náà kún fún àbọ̀ ọ̀rọ̀.

Ohun tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Babalọla sọ ni pé èdè awo ni èdè tó kún inú Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ tí ó si ṣòro fún àwọ́n ọ̀gbẹ̀rì láti túmọ̀. Ó tẹ̀ síwájú pé oríkì kún fún ìtàn lorísìírísìí tí ó nílò àlàyé kíkún láti mú àwọ́n ìtumọ̀ náà jáde. Ẹni tí kò bá wá ní ìmọ̀ ìkọ̀kọ̀ nípa àwọ́n Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ kò leè fún ni ní àǹfààní ìtùmọ̀ wọ̀nyìí.

Oláwálé àti Àránsí (2015, o.i108), fi yé wa pé Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ jẹ́ ọ̀kan gbòógì nínú àwọn ọnà-èdè tó gbajúmọ̀ jù nínú oríkì orílẹ̀ Yorùbá àti pé, ó máa ń ṣàfihàn ìhùwàsí, ìjẹ́ akínkanjú, èèwọ̀, ẹ̀sìn, èrò ìṣèlú,

ọrọ̀-ajé, àṣà àti ìṣe, ibùdo àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí abájọ mìíràn inú ìran kan. Bákan-náà, Agbaje (2001, o.i 120-130), ṣàlàyé pé àwọn apohùn máa ń fẹ́ràn láti lo Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nítorí pé a máa jẹ́ kí oríkì dùn sí i. Ó tẹ̀ síwájú pé àwọn apohùn a máa lo Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ lọ́nà àti má ṣe fi àkókò ṣòfò nípa síso ọ̀rọ̀ tó pọ̀ láàrin ìṣẹ́jú péréte

Lákòótán, onírúurú gbólóhùn ló kúnnú oríkì èyí tó pè fún ìwádìí ìjìnlẹ̀ láti sọ ìtumọ̀ wọn jínlẹ̀ torí pé Yorùbá ní “kò sẹ́ni tó mèdè Àyàn bí ẹni tó mú kọ̀ǹgọ́ ẹ̀ lọ́wọ́, ẹni tó mú Aguda lọ́wọ́ ló mọ ohun t’ómele ń sọ”, àti pé “Ẹni tó mojú Ọ̀wá làá bẹ̀ s’Ọ́wa, ẹnìkankan ò sí mojú Ọ̀wá yàtọ̀ ṣaya Ọba”. Ìdí nìyí tí a fi ṣàwárí àwọn Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ wọ̀nyìí láti rídìí òkodoro.

1.3 Tíọ́rì ìṣàmúlò

Tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀ jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì láti ‘fi ìwádìí ṣe àwárí sí àwọn ohun tó ṣókùnkùn nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀’. Ẹni tí ó dá tíọ́rì yìí sílẹ̀ ni Friedrich Schleiermacher, tí ó sì lò ó fún ìgbà àkọ́kọ́ ní àárin ọdún (1805 sí 1809). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìdásílẹ̀ tíọ́rì yìí wà fún ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn àti ọ̀rọ̀ òfin ṣáájú àkókò yìí, Schleiermacher ni ọ̀pọ̀ gbà pé, ó bẹ̀rẹ̀ sí níí lo tiọ́rì yìí fún àtúpalẹ̀ iṣẹ́ tí ó jẹ mọ́ ìwé kíkọ àti lítíréṣọ̀. Ní ọ̀dọ̀ Schleiermacher, ohun tó jẹ ẹ́ lógún jù ni láti ní ìmọ̀ kíkún lórí iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan pàtó kódà kí ìmọ̀ náà ju ti òǹkọ̀wé lọ. Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe sọ, ohun méjì ni ìlànà yìí fúnka mọ́; àkọ́kọ́ ni ìtúpalẹ̀ gírámà tí í ṣe èdè nínú ohun tó jẹ mọ́ ìtàn nígbà tí ọ̀wọ́ kejì jẹ́ mímọ̀ nípa ìṣètúpalẹ̀ ọkan ẹni tí ó ṣafọ̀ pẹ̀lú ẹ̀wà àti ẹ̀wù inú afọ̀ náà. Ohun tí ó jẹ àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí lógún ni wíwá ìtumọ̀ afọ̀ kan láti orírun afọ̀ bẹ́ẹ̀. Wọ́n gbà pé èso ìròrí aṣàfọ̀ ni afọ̀ jẹ́. À fi kí á wo afọ̀ láwẹ́láwẹ́ láti orísun rẹ̀, kí á tó wò ó lódidi. Eléyìí jẹ́ pé, kí a tó lè mọ gbolóhùn kan nínú iṣẹ́, a níláti mọ gbogbo iṣẹ́ ọ̀hún ni, bẹ́ẹ̀ náà ni kí a tó lè mọ gbogbo iṣé ẹ lítiréṣọ̀ kan, àfi kí a mọ̀ gbólóhùn inú u rẹ̀ lámọ̀dájú.

Agbátẹrù mìíràn lóríi tíọ́rì yìí ni Wilhelm Dilthey (1833-1911). Ohun tí ó ṣe àkíyèsí lórí tíọ́rì yìí ni pé, òun ríi gẹ́gẹ́ bí ogbọ́n sáyẹ́ǹsì fún ẹ̀dá. Ó tẹnu mọ́ pé, nígbà tí sáyẹ́ǹsì gbájúmọ́ ìmọ̀ ohun ìyàlẹ́nu lásán, sáyẹ́ǹsì ẹ̀dá ọmọnìyàn a máa gbájúmọ́ ìrírí ènìyan gan-an. Fuń iṣẹ́ aláwòmọ́ lítíréṣọ̀, ó túmọ̀ sí pé, ayé òǹkàwé àti ìtàn tó rọ̀ mọ́ ọn ló jẹ wọ́n lógún. Ìtumọ̀ ewì tàbí ìwé a máa jáde láti inú ẹni tó kọ iṣẹ́ ọnà yẹ́n pàtó pẹ̀lú ìrírí ayée rẹ̀ gan-an.

Oríṣìíríṣìí àwọn onímọ̀ mìíràn ló tún dá sí ọ̀rọ̀ tíọ́rì ìfìwádìí-ṣètumọ̀ yìí bí àpẹẹrẹ, Hans-Georg Gadamer (1900-2002). Lákòótán,

tíǫ́rì yìí tẹpẹlẹ mǫ́ ọ pé, ìtumǫ̀ kì í ṣe ohun à fọwǫ́ yẹpẹrẹ mú nínú iṣẹ́ lítírésọ̀. Nítorí bẹ́ẹ̀, tíǫ́rì ìfìwádìí-ṣọ̀tumǫ̀ a máa ṣiṣẹ́ tó ju ìtumǫ̀ lásán lọ. A máa ṣe àfikún iṣẹ́ láti túnbǫ̀ mú kí ẹni tó ń ka iṣẹ́ ọna rí ojútùú àwọn ohun tó farasin nínú afǫ̀.

1.4 Ọgbọ́n ìṣèwádìí

Ọgbọ́n ìwádìí tí a ṣàmúlò fún iṣẹ́ yìí ni "ọgbọ́n ìfìwádìí-sọ̀tumǫ̀ nípa ṣíṣe ìwádìí nípa àwọn orí̀kì Aláàfin tí a yàn láàyò, ìtàn tó rọ̀ mǫ́ wọn láti ọ̀dọ̀ méjì nínú àwọn àgbàagba ayaba Aláàfin Ọ̀yọ́ tí wọ́n ti wà pẹ̀lú Aláàfin láti ọdún pípẹ́. Àwọn Ayaba wọ̀nyìí jẹ́ bí ọmọ ọdún méjìlélọ́gọ́ta àti mọ́kàndínláàádọ́ta. Kò sì sí èyí tí kò lò tó ọgbọ̀n ọdún, ó kéré tán pẹ̀lú Aláàfin nínú àwọn méjèèjì. Ìdí mìíràn tí a fi ṣàṣàyàn yìí ni pé, wọ́n mọ àwọn oríkì yìí dáadáa pẹ̀lú ìtumǫ̀. Èyí la rò pọ̀ mǫ́ àwọn ohun tí a gbọ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn asunrárà Ọba tó kù. A gba ohùn wọn sílẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀rọ agbohùnsílẹ̀ ìgbàlódé èyí ti a padà fọwọ́ dà kọ sínú ìwé ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé. Lẹ́yìn náà, a tẹ̀ síwájú láti wá àwọn ìwé péréte tí wọ́n ti sọ̀rọ̀ nípa Aláàfin wọ̀nyìí àti oríkì wọn yálà nínú Jọ́nà àti ojú ayélujára ọ̀ọ̀kan. Gbogbo èyí la pò papọ̀ tí a fi gbé iṣẹ́ yìí kalẹ̀ rekete.

1.5 Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú Oríkì Aláàfin Ládìgbòlù I àtí Adéyẹmi III

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ ló wà nínú oríkì àwọn Aláàfin Ọ̀yọ́ èyí tí ó jẹ́ bárakú fún àwọn oríkì ọ̀hún. Ẹ jẹ́ ká wo oríkì ìsàlẹ̀ yìí bí àpẹẹrẹ:

Ó wá dorí aṣeéperí Gííwá
Ṣàǹbáláyẹ̀wú Aláàfin ìdẹ̀ra
'Dìgbòlù baba Gbádégẹ̀ṣin
A-tó-bí-wọn-tó-perí, Gííwá ọba tíí f'ọba jẹ

Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú àyọlò òkè yìí jẹ́ ọ̀nà méjì. Alákọ̀ọ́kọ́ níbẹ̀ ni orúkọ tí apohùn pe Aláàfin. Dìgbòlù tí ó jẹ́ àgékúrú Ọládìgbòlù- èyí tíí ṣe orúkọ tí à ń pe ọmọ ọlá nílẹ̀ Yorùbá. Ìpìlẹ̀ ohun tí wọ́n yán fẹ́ẹ́rẹ́ mìíràn ni, "ẹni tí ó tó bí àwọn èèyan mìíràn ṣe ń pè é". Nígbà tí ọ̀rọ̀ kẹ̀ta tí a mẹ́nuba jẹ́, ọba tí í fọba jẹ. Aláàfin Ládìgbòlù kiínní lásìkò yìí jẹ́ olórí gbogbo àwọn ọba tí ó sì lagbára láti yọ ọba tàbí fi ọba joyè nílẹ̀ Yorùbá pátá.

Bákan-náà nínú oríkì Aláàfin Dìgbòlu yìí, a tún rí àpẹẹrẹ mìíràn:

O ò r'Ẹdẹ
Aṣeéperí Gííwá ń ṣọkọ ará Ẹdẹ

Babaláàfin, ò r'Èjìgbò
'Dìgbòlù Àkànbí ń sọkọ arán Èjìgbò
Kò r'Ẹdẹ, kò r'Èjìgbò
Ó ń ṣọkọ arán Ògbómọ̀ṣó nílé Ajíléte
Suulọlá, ọmọ ikú,
Ọmọ àrùn
Ọmọ òfò
Ọmọ ìjà
Ọmọ à –dá –bá-ilé
Ládìgbòlù Àkànbí ọmọ àtìmọ́ òde

Àyọlò yìí ń yán ní fẹ́ẹ́rẹ́ bí agbára Aláàfin Ládìgbòlù ṣe tó nígbà náà lọ́hùn-ún tí ó sì ṣe ọlá lórí àwọn ìlú tó kù jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí àyọlò náa ṣe lọ, Aláàfin Ládìgbòlù jókòó lórí ìlúu Yorùbá bi Ẹdẹ, Èjìgbò àti Ògbómọ̀ṣọ́ Ajíleté. Orikì náà tẹ̀ síwájú láti pe Aláàfin ní àwọn orúkọ àpéjẹ́ kan tí a kìí sábà pe ọmọ Yorùbá. Ọmọ ikú, àrùn, òfò, ìjà àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ èyí tí ó ń tọ́ka sí agbára mo lè pa, mo lè dá a sí tí ó wà lọ́wọ́ Aláàfin nígbà náà tí ó sì mu kí àti-onílé àti-àlejo bẹ̀rù ọba náà. Ẹ̀wẹ̀, oríkì bíi:

Ò dékòó ma kọ nọmba
A rè'bàdàn má jẹ̀gẹ́ ọmọ Láwànì o
Aìlérí ogun lójú ẹni ó bá ju Babańlá ẹni lọ́
Babaláàfin, a ò gbọdọ̀ sọ̀rọ̀ ìjà lójú ọmọ elépè Ìṣẹ̀kẹ̀
Ẹni ó bá lérí ogun lójú ọmọ Oyíndàmọ́lá, ọmọ Abíọ́dún
Pàrálábàtá, ọjọ́ tí ò pẹ́ l'Ajẹ́lẹ̀ ó kìlọ̀ fun

Oríkì yìí lo ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ bí o ti ń tọ́ka sí agbára Aláàffin ádìgbòlù kìíní, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, òyìnbó aláwọ̀ funfun ló ń ṣojú àwọn ìjọba ìgbà náà nílẹ̀e. Yorùba sibẹ̀, ọ̀ré ni òyìnbó yìí jé pẹ̀lú Aláàfin. Ìdí sì nìyí tí ó fi jẹ́ pé, bí o tilè wù kí abẹ́rẹ́ àjẹsára ṣe pọn dandan tó láti gbà fún gbogbo ọmọ adúláwọ̀ síbẹ̀. Aláafin kọ̀ láti gbà á nígba ti ó lọ Ekó. Béẹ̀ gẹ́lẹ́ sì ni nígba tí ó lọ sí ìlú Ìbàdàn tí ó sì kọ̀ láti jẹ ẹ̀gẹ́ èyí tí ó jẹ́ oúnjẹ tí ó gbajúmọ̀ jùlọ ní ibẹ̀ dípò bẹ́ẹ̀, Alaafin tẹpẹlẹ mọ́ oúnjẹ ti ó jẹ́ ti Ọ̀yọ́ (Adéyẹmí, 2025, o.i 198-200). Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ mìíràn ni ìlà kẹ̀fà tí ó gbèyìn apẹẹrẹ yìí tí ó ń tọ́ka sí ìbáṣepọ̀ tó rinlẹ̀ èyí tó wà láàrin Aláàfin àti Ajẹ́lẹ̀ Òyìnbó tí a sọ ṣáájú. Ẹni yòówù tí ó bá kojá àyèe rẹ̀ sí Aláàfin yóò fi imú dánrin nítorí àjọṣe tí ó wà láàrin ọ̀rẹ́ méjì yìí.

Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ mìíràn nínú oríkì Aláàfin Ládìgbòlù I ni a rí nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí pé;

Ì bá ṣe pé igi ń sunkún ẹni
Ì bá ṣe pé odò ń sunkún èèyàn
Àt'igi, àt'ọ̀pẹ̀ ní ò bá sunkún ọmọ Sàùdátù

Ohun tí a yán fẹ́ẹ́rẹ́ níbí yìí ni ìfojú inú yàwòrán ipò tí àwọn èèyàn wà nígbà tí Aláàfin Ládìgbòlù tí à ń sọ yìi papòdà torí ìfẹ́ tí wọ́n ní sí i. ó hànde pé Ọba yìí jẹ́ ẹni tí ìlú fẹ́ràn púpọ̀, tí wọ́n sì banújẹ́ nítorí àìsíi rẹ̀ láyé mọ́. Ìdí nìyìí tí apohùn fi sọ pé ká ní ó bá ṣe é ṣe kí igi, ọ̀pẹ̀ sunkún ni, àwọn náà ì bá fi ẹkún ṣèdáro ẹni ire tó jáde láyé tí wọ́ sì ṣàfẹ́rí rẹ̀.

Nínú oríkì Aláàfin Adeyemi kẹta ni a tún ti rí Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ lóríṣìíríṣìí, bí àpẹẹrẹ:

Olórí alábùradà gbogbo ọba Láyíwọlá ọmọ Olúkúewu

Àpẹẹrẹ òkè yìí ń ṣàfihàn Ọba Adéyẹmi gẹ́gẹ́ bí olórí àwọn ọba tókù nílẹ̀ Yorùbá. Èyí ń tọ́ka sí ipò tí Aláàfin yìí wà sí àwọn ọba tókù. Àwọn awuyewuye tó wáyé nígbà ayée rẹ̀ lóríi ta ni olórí àbí ta ló yẹ ní olórí nínú àwọn ọba dá rúkèrúdò sílẹ̀ tán lásìkò náà ṣùgbọ́n àwọn apohùn fi ìdí ẹ̀ múlẹ̀ pe Aláàfin ni ìpẹ̀kun àwọn ọba jákèjádò ilẹ̀ Yorùbá.

Lónìí lọ́la, èké sáré wọ́n relé aláwo
Lónìí lọ́la, èké sáré títí r'òkè ìgbẹ̀tì
Wọ́n d'ífá d'ífá ọwọ́ ọ wọn d'awọ
Wọ́n sàágùn sàágùn, ẹ̀rẹ̀kẹ́ wọ́n d'àpò

Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú àyọlò òkè yìí ń tọ́ka sí akitiyan àwón ọ̀tá Aláàfin tí wọ́n ṣe láti rí i pé àwọn ré̩yìn Ọba. Wón gbìyànjú láti dojú ìjọba rẹ̀ rú, tí wón sì relé àwọ́n adáhunṣe àti olóògùn. Wọ́n sa òògùn yìí títí ṣùgbọ́n wón kò rọ́nà àbáyọ títí wọ́n fi padà wá gbà fún Olódùmarè tí ó fi ọba jẹ.

Pẹ́lẹ́ńgẹ́ bíi Fúlàní baba Làtífá.

Ìlà yìí ń júwe ìrísí ọba Adéyémí kẹta. A yán an fẹ́ẹ́rẹ́ nípa ṣíṣe àfiwée rẹ̀ pẹ̀lú ìrísí àwọn ẹ̀yà Fúlàní tí a gbàgbọ́ pé èèyàn tẹ́ẹ́rẹ́ ni wọ́n sábà ma ń jẹ́. Nígbà tí Aláàfin Adéyẹmí náà sì ti jẹ́ èèyàn tẹ́ẹ́rẹ́, ó rọrùn láti dọ́gbọ́n sọ fún ni láti ara yíyán ọ̀rọ̀ fẹ́ẹ́rẹ́.

Igbá túúbá,

Àwo túúbá
Ìsaasùn tó lóun ò níí túúbá
Làmídì Àtàndá, iná ó f'ojú ẹ̀ rí màbo!

Bákan náà, nínú oríkì òkè yìí fún Aláàfin, a tún ṣe ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nípa sísọ̀ ohun tó ṣẹlẹ̀ lójú ayé ọba nígbà tí àwọn apákan gbạ láti forí balẹ̀ fún un tí àwọn mìíràn sì kọ̀ láti ṣe bẹ́ẹ̀. Oríkì yìí, bí kò tilẹ̀ dárúkọ ń tọ́ka sí ohun tó ṣẹlẹ̀ sí àwọn tókù tí wọ́ fojú di ọba. Àwọn yìí ni oríkì tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìsaasùn nígba tí àwọn tó gbà fún ọba jẹ́ igbá àti àwo.

Ọmọ ládé làdè ládé, Aláàfin Ọ̀yọ́ ládé
Adé tó o ní, ọmọ Adé lô kúkú ń pín fún gbogbo wọn
Kò séyìí tó tó t'Aláàfin jìnwìnnì bí owó ẹ̀yọ̀

Oríkì yìí ń sọ ìtàn nípa Adé Aláàfin léréfèé. Ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ ìlú Ifọ́n níbi tí a gbà pé ìbẹ̀ ní Adé Aláàfin ti wá. Nínú oríkì ìlú Ifọ́n ní ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun àti Ifón Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, wọ́n a máa kì wón pé:

Ọmọ ládé làdè ládé
Aláàfin ò ládé
Adé Òrólú la gbà f'Aláàfin (Oríkì Ifọ́n Ọ̀ṣun)
tàbí
Ọmọ ládé làdè ládé
Aláàfin ò ládé
Adé Aládìíkún la gbà f'Aláàfin (Oríkì Ṣẹ̀pẹ̀tẹ̀rí)

Tí a bá wo àwọn oríkì mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìị láwòjinlẹ̀, a ó rí i pé, gẹ́gẹ́ bí ohun tí a mọ̀ mọ ìtàn àtẹnudẹ́nu nílẹ̀ Yorùbá, bí kò bá lé kún, a sì dínku àti pé púpọ̀ nínúu wọn máa ń ṣègbè fún ìran kan tàbí òmíràn ni. Ìtàn sọ pé, Adé Ifọ́n tí a mọ̀ sí Adé Òrólú yìí ni a gbà fún Aláàfin nínú oríkì yìí. Adé yìí ṣe pàtàkì débi pé òun náà ni ọba Ọ̀ọ̀ni máa ń dé èyí tí a tún mọ̀ sí Adé Arè. È gbọ́ bí Oláwálé àti Àránsí ṣe

> Ade Arè yìí kan náà ni Ọba Ọ̀ọ̀ni máa ń dé lọ sí 'mògún'. Alábẹ̀bẹ̀ kò sì gbọ̀dọ̀ dáwọ́ dúró tí Adé yìí bá wà lórí Ọ̀ọ̀ni láti má gba eṣinṣin láàyè láti bà lé e nítorí pé igbàgbọ́ ni pé tí eṣinṣin tó bà lé Adé yìí bà lé ẹnìkan, ẹni náà yóò kọlà Ṣànpọ̀nná ní ọdún náà. Adé yìi, ti ìsẹ̀ǹbáyé ni… (Olawale àti Àránsí 2015, o.i. 113-114)

Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú oríkì òkè yìí ń fi yé wa pé Aláàfin papàá ní Adé tiẹ̀ tó ń fún àwọn ọba kéékèèké abẹ́ẹ̀ rẹ̀. Ó tún fi yé wa pé 'ọmọ adé' ni Aláàfin pín fún gbogbo àwọn ọba tókù, èyí tó túmọ̀ sí pé Adé tí Aláàfin ní gan-an pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ tó fi jẹ́ wí pé àwọn tó kéré níbẹ̀ ni ó ń pín fáwọn ọba abẹ́ ẹ rẹ̀ tí èyí sì tako oríkì tí àwọn Ifón sọ pé Adé ìlúu tiwọn la gbà f'Aláàfin. Ìtẹ̀síwájú nínú oríkì Aláàfin Adéyẹmi kẹta fi kún un pé àẉọn ọba kan wà tí Aláàfin fún ládé lóòótọ́ èyí tó fìdí ẹ̀ múlẹ̀ pé bẹ́ẹ̀ gẹ́lẹ́ ni ọ̀rọ̀ ṣe rí. Ẹ wo oríkì yìí:

Òjò ṣùùrùrù l'ójọ́ tóo f'Óńjò ládé Bàbá Mosúnmọ́lá
Òòrùn gangan lo f'ólu Ìnáṣà ládé ọkọ Ràhímọ́tù
Onítedé, Asẹ́yìn, Iba Kìṣí,
Onítedé, Asẹ́yìn, Iba kìṣí,
Gbogbo wọn lô dé ládé porongodo
Apènà, ìwọ ni baba gbogbo àwọn ọba

1.6 Àgbálọgbábọ̀

Ó hàn síta pé ewì kíké, rárà sísun, oríkì àti gbogbo ewì alohùn pátá tí àwọn apohùn bíi asunrárà, akùnyùngba, akígbe ọba, asunjálá àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ máa ń ṣe ló kún fún ọ̀pọ̀ ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ tí ó sì nílò ìwádìí si nítorí pé àwọn ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn wọ̀nyìí ń ṣatọ́nà fún ìtàn kan tàbí òmíràn tí ó farasin ni. Gbogbo ìwádìí ìjìnlẹ̀ láti túmọ̀ ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ tí ó farasin nínú àwọn oríkì tí a yàn láàyò nínu iṣẹ́ yìí ni a gbéyẹ̀wò fún àǹfààní ìmọ̀ ọ̀jọ́ iwájú. Iṣẹ́ yìí fi kún ìmọ̀ wa lórí oríkì àwọn ọba nílẹ̀ Yorùbá ní pàtàkì àwọn Aláàfin méjì tí a yàn láàyò nínú iṣẹ́ yìí. Nípa ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú oríkì wọn a rí àwọn ohun tí ó ṣeéṣe kí a má fọkàn sí lásìkò tí à ń gbọ́ oríkì ọ̀hún, nígbà tí oríkì bá ti dùn mọ́ ni, ṣùgbọ́n a rí irú àwọn ọ̀rọ̀ àti gbólóhùn wọ̀nyìí látàrí fífi ìwádìí ṣètumọ̀ àwọn ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ inú àwọn oríkì yìí bí wọ́n tilẹ̀ forímù. Nípa ìwádìí, a rí i pé, oríkì nílẹ̀ Yorùbá kọjá ìgbádùn àti ìmóríwú lásán, ńṣe ni ó tún ma ń sọ ìtàn tí ó sì máa ń tú àṣírí àwọn ohun wọ̀n-ọn-nì tí a kò ṣàkíyèsí rẹ̀ tẹ́lẹ̀. Nínú oríkì Òba Ládìgbòlù kìíní àti Òba Adéyẹmí kẹta, ìfìwádìí sọ̀tumọ̀ àwọn ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ nínú oríkì wọn jẹ́ kí á rí agbára wọn, ipò tí wọ́n wà nígbà-náà gẹ́gẹ́ bí olórí, ogun tí wọ́n jà, ìrísí wọn, ibi tí ilẹ̀ àti ọlá Aláàfin dé àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ

Ìwé Ìtọ́kasí

Adeyemi, R.O. (2025). *"A speech act study of Rárà Aláàfin Ọ̀yọ́".* Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and Nigerian Languages.

University of Ilorin, Ilorin, Nigeria.

Ajayi, W. B. (1995). "Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ Nínu Oríkì Orílẹ̀ Àṣàyàn Àwọn Ọba Aládé Èkìtì" Ph.D. Thesis, Department of African Languages and Literatures, Obafemi Awólọ́wọ̀ University, Ile Ifẹ̀.

Babalolá, S.A. (1966). *The content and forms of Yoruba Ijala.* London: Oxford University Press.

Babalọlá, S.A. (1967). *Àwọn Oríkì Orílẹ̀*. Glascow: Collins.

Finnegan, R. (1977). *Oral Literature: Its nature, significant and social context*. New York: Cambridge University press.

Gadamer, H.G. (2004). *Truth and method* (J. Weinsheimer & D. G. Marshall, Trans.). Continuum. (Original work published 1960).

Ilésanmi, T. M. (1977). *Oral Poetry*. London: Cambridge University Press.

Ilésanmi, T. M. (1989). "Sub-ethic Interaction in Yorùbá Oríkì: The Ijesa Example". In *Seminar Series, No. 2* Department of African Languages and Literatures, Obafemi Awolowo University, Ilé-Ifẹ̀.

Ilésanmi, T. M. (1990). *Oríkì Orílẹ̀ Ìjèṣà2.* (Mimeography). Department of African Languages and Literature, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀

Olátúnjí, O. (1984). *Features of Yorùbá oral Poetry.* Ìbàdàn: University Press Limited.

Ọláwálé, H. àti Àránsí, O.A. (2015). "Ìfìwádìísọ̀tumọ̀ Àwón Ìyánrọ̀fẹ́ẹ́rẹ́ Inú Oríkì Àwọn Ìlú Ajọrúkọmọ́-Ifọ̀n". Nínú *Èdè, Àṣà àti Lítírẹ́ṣọ̀ Yorùbá: Ìtàn-ò-ní-gbàgbé yín: Olóyè Diípọ̀ Gbénró àti Alàgbà Fúnṣó Fátókun.* Orí kẹ̀wàá 107-122. Ìbàdàn: Masterprint Publishers. ISBN 978-978-618-479-8.

Schleiermacher, F. (1998). *Hermeneutics and criticism.* (Andrew Bowie, Trans.). Cambridge University Press. London.

Wilhelm, Dilthey. (1833-1911). In Makkreel, R.A., (1975). *Dilthey: philosopher of the Human Studies*. New Jersey: Princeton University Press.

Wolff, H. (1962). Rárà: A Yorùbá chant. *Journal of African languages 1(1) ,45-56.*